# ELÉYÌÍ NII ÌPÌLẸ̀

# O DI ỌWỌ RẸ IRẸ ARẸWÀ ILE ADÚLÁWỌ̀



IRE OBÌNRIN MUSULUMI, IRE ODODO TO WA NI ORÍLẸ̀ ADULAWO, OLOHUN OBA SE Ọ NI ENI APONLE  ENI AABO , OSI SE O LOSO PELU ISLAM ATI IGBAGBO, Ó SI FÚN Ọ NÍ ÀWỌN OJÚṢE TÍ Ó .TOBI FÚN ISEMI RẸ ATI ÀWÙJỌ RẸ

AKO SILE YII , YIO TAN IMOLE SÍ ÀWỌN OHUN PÀTÀKÌ TÍ O NILO GẸ́GẸ́ BÍ ÀWỌN ITOSONA FÚN IGBAGBO RẸ, ÀTI ÀWỌN ÌJỌSÌN RẸ, ÀTI ÌWÀ RẸ, .ATI OJÚṢE RẸ LATI TUN ÀWÙJỌ ẸṢÌN SE

## ALAKOKO:- ÌGBÀGBỌ́ OBÌNRIN MÙSÙLÙMÍ

### KÍ NI A Ń PÈ NÍ ADISỌKAN?

ADISỌKAN NI NÍNÍ ÌGBÀGBỌ́ ÒGIDÌ SI ỌLỌHUN ỌBA ỌKAN SOSO, ATI GBÍGBA ÀWỌN MỌLAIKA RẸ GBỌ́ , ÀTI ÀWỌN ÌWÉ RẸ, ÀTI ÀWỌN OJISẸ RE, ATI ỌJỌ́ ÌKẸYÌN, ATI GBIGBA KÁDÀRÁ GBÓ BOYA NI DÁRADÁRA TÀBÍ ABURÚ.

OHUN NI IPILE TI WỌN MỌ ISẸMI RẸ LÉ LÓRÍ, GBOGBO ÌGBÀ TI IGBAGBO YII BATI NII ÀLÀÁFÍÀ ATI AGBARA,

IRE NÁÀ YIO DI OLUFAYA BALE ATI OLÚDÚRÓ SINSIN JÙLỌ.

ÀWỌN ORIGUN ÌGBÀGBỌ́ , ÀTI PÀTÀKÌ RẸ NÍNÚ ISẸMI RẸ :-

**1- NINI ÌGBÀGBỌ́ SÍ ỌLỌHUN ỌBA ỌKÀN ṢỌṢO TI KÒ SÍ OROGÚN FÚN UN**

- DÁJÚDÁJÚ ỌLỌHUN NÁÀ NI ỌBA ỌKÀN ṢỌṢO,TÍ KOSI OROGÚN FÚN NINU ÌJỌBA RẸ̀, ATI NIBI ÌJỌSÌN RẸ̀.

- Ó DI ÒRANYÀN KI O GBÁRA LÉE NI ÒHUN NÌKAN SOSO, KÍ O MÁSE BẸ̀RÙ OHUN KÓHUN YÀTỌ̀ SII, KÍ O SI MASE RANKAN OHUN KÓHUN YÀTÒ SÍ ÀÁNÚ RẸ.

ỌLỌHUN ỌBA SỌ PÉ:- (SỌPE ỌLỌHUN ỌBA ỌKÀN ṢỌṢO NI,ỌLỌHUN ỌBA AJIRONUKAN, KÒ BÍMỌ ẸNÌ KAN KAN KÒ BÍI, KÒ SÌ SÍ ẸNIKẸ́NI TÍ Ó JÉ AMUGBA LẸGBẸ FÚN UN) SUUROT LI- IKHILAAS: 1-4)

### 2- NÍNÍ ÌGBÀGBỌ́ SÍ ÀWỌN MỌLAIKA

-ÀWỌN MỌLAIKA JE ẸRÚ ỌLỌHUN ALAPỌNLE, WỌN KÌÍ DẸ́ṢẸ̀ SÍ ỌLỌHUN ỌBA WỌN , NINU WON NII:- JIBRIIL ELEYI TO MA N SO IMISI KALẸ. ÀTI MIKAAHIIL, ATI ISROOFIIL, ATI MALAIKA TO MA N GBA EMI.

Ó DI ÒRANYÀN KÍ O NÍ ÌGBÀGBỌ́ PÉ WỌ́N NBẸ, ṢÙGBỌ́N MÁ SE TỌRỌ OHUN KÓHUN LỌ́WỌ́ WỌN, DÁJÚDÁJÚ ỌLỌHUN NÌKAN NI A MÁA Ń DOJÚ ÀDÚRÀ KỌ.

**3- NÍNÍ ÌGBÀGBỌ́ SÍ ÀWỌN ÌWÉ TÍ WỌ́N SỌKALẸ LÁTI SANMỌ**

ALI - QURÃN JẸ́ ỌRỌ̀ ỌLỌHUN ELÉYÌÍ TÍ WỌN KÒ LEÈYÍ , OHUN NI IPILẸ ITOSONA FÚN Ọ NÍBI GBOGBO ALAAMORI ISEMI RẸ.

Ó DI ÒRANYÀN KÍ O ṢIṢẸ́ TỌ̀Ọ́, KÍ Ó SÌ MỌ ÌTUMỌ RẸ, KÍ O SÌ MÚ-UN NÍ ALABARIN RẸ NI GBOGBO ÌGBÀ.

**4- NINI ÌGBÀGBỌ́ SÍ ÀWỌN OJISẸ**

GBOGBO OJISE ỌLỌHUN NI WON WA PELU IPEPE SI OJU ỌNA MÍMỌ ỌLỌHUN NÍ ỌKAN ṢOṢO,

ANABI MUHAMMAD KI IKE ATI OLA OLOHUN MÁA BÀA, SÌ NI Ó PARI ÌPÈPÈ NÁÀ.

WỌN KII JỌ́SÌN FUN ÈYÍKÉYÌÍ NÍNÚ WỌN, ṢÙGBỌ́N KÍ Á TẸLE WỌN, KÍ Á SÌ PỌN WỌN LÉ, A KÒ SÌ GBỌDỌ GBÉ ÈYÍKÉYÌÍ NÍNÚ WỌN KỌJÁ ÀÀYÈ RẸ..

**٥- NINI ÌGBÀGBỌ́ SÍ ỌJỌ́ ÌKẸYÌN**

OHUN NI ỌJỌ ÌṢIRÒ, NIBI TI WỌN YÓÒ TI SAN GBOGBO ỌMỌ ÈNÌYÀN NÍ ẸSAN IṢẸ́ RẸ, TORINAA ṢE ÌṢE FÚN OHUN TÍ Ó WÀ LE YIN IKU, KÍ O SÌ JẸ KÍ GBOGBO ISEMI RẸ JẸ́ ÈYÍ TÍ YÓÒ MÚ Ọ WỌ ALUJANNA.

**٦- NINI ÌGBÀGBỌ́ SÍ KÁDÀRÁ DÁRADÁRA RẸ ÀTI ABURÚ RẸ**

GBOGBO OHUN TÍ Ó BÁ ṢẸLẸ̀ SÍ Ọ NÍNÚ ISẸMI RẸ OTI WA NI ÀKỌSÍLẸ̀ LỌDỌ ỌLỌHUN, MÁSE BẸ̀RÙ ÀWỌN ABURÚ, MÁ SÌ SE JAKAN KÚRÒ NÍNÚ IKE ỌLỌHUN, DÁJÚDÁJÚ GBOGBO OHUN TÍ ỌLỌHUN BÁ YÀN FÚN Ọ NI OORE, KODA KÍ O MÁ GBỌ̀ AGBỌYE RẸ̀ BÁYÌÍ.

**<u>ÀWỌN AṢỌ TẸ́LẸ̀ FUN FIFI ẸSẸ̀ ÌGBÀGBỌ́ RINLẸ NÍNÚ ỌKÀN RẸ:-</u>**

✓□ MÚ AL- QURÃN NI ALABARIN RẸ, TORÍ PÉ OHUN NI IMOLE TI YIO MÁA TÀN SÍNÚ ỌKÀN RẸ.

✓□ MÁA TẸRA MỌ́ṢÍṢE GBÓLÓHÙN IRANTI ỌLỌHUN, TORÍ PEE OHUN NI YÓÒ MÁA SỌ ÌGBÀGBỌ́RẸ KÚRÒ NÍBI LÍLẸ.

✓□ KỌ́ÌMÒ NÍPA ADISỌKAN RẸ LÁTI INÚ ÀWỌN IPILE TO NI ÀLÀÁFÍÀ, KÍ O SÌ JÌNÀ SÍ ÀWỌN ADAKADAALẸ ÀTI ÀWỌN OHUN ÀGBÉLẸR

## ELEEKEJI:- ÀWỌN OJÚṢE OBÌNRIN MÙSÙLÙMÍ

**١- MÍMỌ́ SỌ́ ÀSÌKÒ ÌRUN**

* IRUN KIKI JE OHUN TÍ Ó SO Ọ PAPỌ MỌ ỌLỌHUN, OHUN SI NI ÀKỌ́KỌ́ ÌBÉÈRÈ TI WỌN YÓÒ BI Ọ NI ỌJỌ ÌGBÉNDE.

* MASE JE KIN NKANKAN DI Ọ LỌWỌ LÁTI LỌỌ LÁRA , GẸGẸ BÍ OSE NI AKAKUN ỌRỌ ÌGBÉSÍ AYÉ RẸ, MÁA ṢE

ÀKÓLÉYÀ IRUN LỌPỌLỌPỌ,  TORI PE OHUN NII IPILE ORIRE RẸ.

OJISE ỌLỌHUN OBA SỌRỌ KI IKE ATI OLA MAA BA:- (ISẸ TI ỌLỌHUN OBA NIFẸ SÍ JÙLO NI ÌRUN KÍKÍ LÁSÌKÒ RẸ). (IMAAMU BUKHAARYY ÀTI MUSILIMU NI WỌN GBAA WA).

**2- AṢỌ IJAABU ATI NÍNÍ ÌTÌJÚ**

•* LÍLỌ AṢỌ IJAABU JE ADÉ ÌKÓ ARA ẸNI NÍ ÌJÁNU, Ó SI JE ÀṢẸ LATI ÒDÒ ỌLỌHUN FÚN ÌSÒ RẸ, KÌÍ SE ÁSÀ LÁSÁN.

* MÁ SE GBA ENI TÍ Ó BÁ PEE NÍ ÒǸDÈ GBÓ, TORÍ PÉ DÁJÚDÁJÚ IYÌ NII, OHUN NÁÀ SÌ NI YÓÒ SEE ADAYANRI RE GÉGÉ BÍI OBÌNRIN MÙSÙLÙMÍ ALAPỌNLE

ỌLỌHUN ỌBA TÍ Ó GA SỌ PÉ :- *(MO PE IRẸ ANABI, SỌFÚN ÀWỌN ÌYÀWÓ RẸ, ATI ÀWỌN ỌMỌ RẸ OBÌNRIN, ATI AWỌN OBINRIN MÙSÙLÙMÍ PÉ KÍ WỌN MAA WỌ AṢỌ AMUTAN WỌN ELEYI NI YIO JẸ́ KI WỌN MO PE OLUGBAGBỌ ODODO NI WỌN, WỌN KO SI NI MAA FII SUTA KÀN WỌN).

(SURATUL AHZAAB: 59)

**٣- ṢÍṢE DÁRADÁRA SÍ ÀWỌN ÒBÍ MÉJÈÈJÌ ATI SI AWON ARÁ ILE**

* ÌYỌ́NÚ ỌLỌHUN OBA N BẸ NIBI ÌYỌ́NÚ ÀWỌN ÒBÍ MÉJÈÈJÌ, SE OJÚ KÒKÒRÒ LÁTI ṢE DÁADÁA SÍ WỌN KÍ OSI ṢE BÍ ẸRÚ SÌN WỌN, KÍ O SÌ MAA MU INU AWỌN MÉJÈÈJÌ DÙN.

* MÁ SE MAA GBE OHUN RẸ SÓKÈ SÍ WỌN, KÍ O MAA TẸLE AṢẸ WỌN, YATỌ SI EYI TOLE MU Ọ DẸṢẸ SII

## 4- ÌWÀ RERE PẸ̀LÚ SÍSỌ AHANlangue

* MÁ SE SỌ ỌRỌ̀ ẸNIKẸ́NI LẸYÌN, KÍ O SI MA SE SỌRỌ ẸNIKẸ́NI NÍ ABURÚ, TORÍ PÉ GBOGBO ỌRỌ̀ TÍ O ŃJÁDE LÁTI ẸNU RẸ NI Ó WÀ NÍ ÀKỌSÍLẸ̀ FUN Ọ.

ÒJÍṢẸ ỌLỌHUN ỌBA KI IKE ATI ỌLA MAA BA SỌ PÉ:- ( MÙSÙLÙMÍ NI ẸNI TI MÙSÙLÙMÍ ẸGBẸ́ RẸ̀ LÀ KÚRÒ NÍ IBI ABURÚ AHÁN RẸ̀ ÀTI ỌWỌ RẸ,) (BUKHAARYY ÀTI MUSILIMU LOGBAA WÁ)

## 5- ÌFỌKÀNTÁN PẸ̀LÚ ÒDODO

* JẸ OLÓDODO NÍBI IṢỌRỌ RẸ ATI ÌSESÍ RẸ,  ATIPE ÒDODO JE OKAN NINU AWỌN ÀPẸRẸ ONÍGBÀGBÓ.

* MA SE TAN ẸNIKẸ́NI, MA SÌ SE ÌJÀMBÁ NIBI OJA TABI IṢẸ, TABI NI IBI ÈYÍKÉYÌÍ ÀJỌṢE RẸ PẸ̀LÚ ẸLÒMÍRÀN.

## ELEEKETA:- OJÚṢE OBÌNRIN MÙSÙLÙMÍ LATI TÚN ÀWÙJỌ SE

ÌWỌ KII SE ÈNÌYÀN LÁSÁN NÍNÚ ÀWÙJỌ, BI KO SEPE Ó JE OLUSEDA ÀWỌN ORÍṢIRÍṢI ÌRAN ÈNÌYÀN, ÀTI ẸNI TÍ YÓÒ MÁA LAPA LÁRA GBOGBO ẸNI TOWA NII AGBEGBE RẸ.

## 1- RÍRE ÀWỌN ỌMỌ SÌ OJÚ ỌNA ISLAM

* IWO NI ILE ÈKÓ ÀKỌ́KỌ́ FÚN ỌMỌ RẸ, REE SI ORÍ ÌFẸ́ TI ỌLỌHUN ÀTI TI ÒJÍṢẸ RẸ, ATI SI ORI IWA TO DÁRA JÙLỌ.

* KỌ ỌMỌ RẸ NIPA KIKI ÌRUN LÁTI KÉKERÉ,  KÍ O SÌ JẸ AWOKỌṢE DÁADÁA FÚN-UN NIBI GBOGBO NKAN.

## 2- SÁRÉ NÍPA WÍWÁ IMỌ

* ÌMỌ̀ JẸ́ ÌMÓLẸ̀, YALA  ÌMỌ̀ NÍPA ÒFIN ỌLỌHUN ỌBA TABI ÌMÒ NIPA AYÉ, TORINAA MÁA SE OJÚ KÒKÒRÒ WÍWÁ ÌMỌ̀ NÍ GBOGBO ÌGBÀ .

* OJISẸ ỌLỌHUN ỌBA KI IKE ATI ỌLÁ MÁA BÁ A SỌ PÉ :- "ẸNI TÍ Ó BA TỌ OJÚ ỌNA KAN, TÍ Ó TI NRI ÌMỌ, OLOHUN ỌBA YIO SỌ ỌNÀ ALI- JANNAH DI IRỌRUN FUN" (MUSILIMU LOGBAA WA).

**3- ṢÍṢE ÀTÚNṢE LÁÀRÍN ÀWỌN ÈNÌYÀN**

* JẸ OKÙNFÀ TI ÀLÀÁFÍÀ YÓÒ FI TÀN KA, MÁ SE JẸ ÌPÌLẸ̀ WAHALA ATI AIGBỌRA ẸNI YE.

* ṢE OJÚKÒKÒRÒ L'ORI PÍPA INÁ ÀWỌN IFANFÀ, KÍ Ó SÌ MÁA FAN RERE Ẹ̀MÍ ÌFẸ́ ÀTI ÀMÓJÚKÚRÒ KÁ ÀÁRÍN ÀWỌN ÈNÌYÀN.

**4- KÍ KÓPA NÍNÚ IṢẸ́ OLÓORE**

* MÁA RÀN ÀWỌN ALÁÌNÍ LỌWỌ, KÍ O SÌ JẸ ÒNÍBO ASIRI FÚN ÀWỌN TÍ WÓN NÍ BÙKÁTÀ, KÍ O JẸ ẸNI TI YÓÒ MÁA FAN OORE KA PẸLU GBOGBO OHUN TÍ O BA NI NIKAPA.

- MA SE FI OJÚ KÉRÉ ÈYÍKÉYÌÍ IṢẸ OLÓORE, KODA TÍ O FI DE IBI ỌRỌ TO DARA, NINU IṢẸ ASE GBỌRẸ NI.

**5- KÍ O JẸ ÀWÒ KOSE DÁRADÁRA**

* KO TII TO FUN Ọ LATI MAA SỌRỌ NI PA DÁADÁA, BIKO SE PE O DI ÒRANYÀN FUN Ọ LATI LO IṢẸMI NINU RẸ PẸLU AWỌN ISESI RẸ.

* JE AWO KOSE DÁADÁA FÚN OBÌNRIN MÙSÙLÙMÍ TÍ O YEGE,  ELEYI TI O ŃṢE DÉÉDÉÉ LÁÀRIN ESIN RẸ ATI IṢẸMI RẸ. GẸGẸ BÍ ÀWỌN IYA AWỌN MU'MINI KI ỌLỌHUN BAWA YONU SI WỌN.

## NI ÌPARÍ:- IRẸ ÒDÒDÓ ALALUBARIKA

DÁJÚDÁJÚ ẸṢIN ISLAM TI FI Ó SÌ ÀÀYÈ APỌNLE, Ó SI GBE Ọ GA, Ó SI SE Ọ NI IMỌLẸ FÚN ÀWÙJỌ RẸ, MA SE FI OJU KERE OJÚṢE RẸ, MÁ SI SE GBA ẸNIKẸ́NI LÁÀYÈ . LATI FI OJÚ KERE IPO RẸ

JẸ ẸNI TO F'ẸSẸ RINLẸ LORI ẸṢIN RẸ, TOSI DURO ✓ SINSIN PẸLU AṢỌ IJAABU RẸ, P

.ṢE IYANRAN PELU KIKO ARA DURO

MA ṢE GBA ITANJẸ PẸ̀LÚ ÀWỌN OHÙN ÌRÚJÚ, KÍ O ✓ SI MAA RÁNTÍ NI GBOGBO IGBA PE OLORI APỌNLE FUN .Ọ NI PE O JẸ OBINRIN MUSULUMI

ṢE ÌPÈSÈ ORIPA TÍ Ó MỌ FÚN ARA RE, KI O SI MAA ✓ JẸ KI EMI RẸ DÌRỌ MỌ ỌLỌHUN, DÁJÚDÁJÚ OHUN NI .KII MU ẸNI TOBA DOJUKỌ PỌWỌFO

IRẸ ỌLỌHUN SE WA NI ỌKAN NÍNÚ ÀWỌN OBÌNRIN RERE, KÍ O SI FI ẸSÈ WA RINLẸ̀ LORI ÀṢẸ RE, KÍ O SI SE ،WA NI OKÙNFÀ FIFAN DÁADÁA KÁ

ỌLỌHUN SE IKẸ ATI ỌLA FÚN ANABI MUHAMMAD ATI AWỌN ARA ILE RẸ, ATI AWỌN SAABE RẸ LAPAPỌ.

# ELÉYÌÍ NII ÌPÌLẸ̀

# O DI ỌWỌ RẸ IRẸ ARẸWÀ ILE ADÚLÁWỌ̀

